# Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe Èdè Yorùbá

**Oyè Táíwò**
*Yunifásítì Ìbàdàn*
*oyepaultaiwo@gmail.com; po.taiwo@mail1.ui.edu.ng*

àti

**ỌLAKOLU, Oluwatoyin Titilayo**
*Adeyemi College of Education, Ondo, Ondo state*
*08067392364, tititoyin@gmail.com*

**Àsamọ̀**

Ọ̀kan pàtàkì ni àpólà ìṣe (APIṢ) jẹ́ nínú ìhun gbólóhùn, kòṣeémánìí ni pẹ̀lú. A lè ki í gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àsópọ̀ ọ̀rọ̀ tí ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ orí rẹ̀ tí a sì lè lò gẹ́gẹ́ bí kókó gbólóhùn nínú gbólóhùn aṣeégbà. Yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó jẹ́ kànńpá nínú ìhun àpólà ìṣe, a tún lè ya àwọn ẹ̀pọ́n sọ́tọ̀ tí wọ́n jẹ́ ìwọ̀fún nínú ìhun àpólà ìṣe. Ẹ̀pọ́n ni ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí ó ń ṣe òdiwọn ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe. Àwọn ẹ̀pọ́n tí ó ń pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe ni *ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe* àti *ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe*. A rí lára àwọn ẹ̀pọ́n wọ̀nyí tí wọ́n máa ń mú kí ìtumọ̀ *ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí* pé, àwọn ni mo pè ní *ẹ̀pọ́n aṣàmúpé*, irú wọn jẹ́ kànńpá fùn ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀, àwọn ẹ̀pọ́n kan máa ń fi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, àwọn ni mo pé ní *ẹ̀pọ́n aṣàfikún*, wọn kìí ṣe kànńpá, ìwọ̀fún ni wọ́n fún ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí. A ṣàlàyé àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe, ipa tí wọ́n ń kó àti bí àwọn ẹ̀pọ́n ṣe máa ń jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe.
***Ọ̀rọ̀ atọ́nisọ́nà***: *ẹ̀pọ́n aṣàfikún àti aṣàmúpé, ìjẹyọpọ̀ ẹ̀pọ́n, ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, èdè Yorùbá*

## Modifiers in the Structure of Yoruba Verb Phrase (VP)

**Abstract**

The verb phrase is one of the most important constituent of the sentence which a sentence cannot do without. It can be defined as a word or conbimation of words headed by a verb and used as the predicate in a grammatical sentence. Apart from the verb, which is the obligatory constituent of the verb phrase, we can also distinguish optional modifiers. A modifier is a word or phrase that specify the meaning the head verb in the verb phrase. Modifiers in the verb phrase are pre-verbal and post verbal modifiers. Some of these modifiers complement the head word, i.e. the verb, we refer to them as verbal complements, they obligatorily occur with the head verb they complement in the verb phrase. The other modifiers add to the meaning of the head verb; they are reffered to as optional adjuncts. In this paper, I explain role of these modifiers and their distribution in the verb phrase.
***Keywords:*** *adjunct and complement modifiers, co-occurrence of modifiers, head verb, Yorùbá language.*

## Ìfáárà

Ọ̀kan pàtàkì ni àpólà ìṣe (APIṢ)[1] jẹ́ nínú ìhun gbólóhùn, kòṣeémáàní ni pẹ̀lú. Ìdí ni pé nínú rẹ̀ ni gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀, ìrírí àti ìṣe ti gbólóhùn gbé jáde sodo sí. Àpólà ìṣe, àpólà orúkọ àti àpólà apàrísídà ni wọ́n papọ̀ di gbólóhùn. Ní ìgbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, àpólà ìṣe nìkan a máa dá dúró gẹ́gẹ́ bí gbólóhùn. Àmọ̀ ohun tí ó dájú ni pé bí a bá yọ àpólà ìṣe kúrò nínú gbólóhùn, àkùdé ti dé bá irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀, kìi ṣe gbólóhùn mọ́.

## Ìmọ̀ àti Ẹ̀kọ́ Àtẹ̀yìnwá nípa Ìhun Àpólà Ìṣe

Àwọn onímọ̀ ti ṣàlàyé ìhun àpólà ìṣe nínú èdè Yorùbá. Bamgboṣe (1966, 1967, o.i.18-23, 1990, o.i.154-158) kò fún àpólà ìṣe ní oríkì ṣùgbọ́n ó fi yé wa pé fọ́nràn márùn-ún ni ó wà nínú àpólà ìṣe, àwọn ni aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ ìbẹ̀rẹ̀, ọ̀rọ̀-ìṣe kíkún, ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ ìparí àti agbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-ìṣe. Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Ayọ Bamgboṣe ní aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe ni ọ̀rọ̀-ìṣe tí kò lè dá dúró, ṣùgbọ́n tí ọ̀rọ̀-ìṣe mìíràn gbọ́dọ̀ tẹ̀lé nínú àpólà-ìṣe, àpẹẹrẹ wọn ni ẹ̀rún ọ̀rọ̀-ìṣe *ń* tí ó jẹ́ atọ́ka ìbá-ìṣẹ̀lẹ̀. Aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aláìbárarìn, wọ kò lè jẹ yọ pa pọ̀ nínú àpólà ìṣe bí àpẹẹrẹ *ìbá, bá, ìbáà, gbọ́dọ̀, yóò/yó/ó, á, máa/ma, a.* Aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe abárarìn, wọ́n lè jẹ yọ pọ̀ nínú àpólà ìṣe, àwọn ni *tiẹ̀, sáà, kọ́/kọ́kọ́, mà, sì/dẹ̀, kàn, kúkú, wulẹ̀, sì/ì, dédé, ti, ti / gbé, fi, ṣe, túnbọ̀, wulẹ̀, ṣẹ̀ṣẹ̀, jàjà, tètè, mọ̀ọ́mọ̀, jùmọ̀, nìkan, tún, fẹ́rẹ̀, sáábà, lè, máa/ma.* Aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe kẹrin ni atọ́ka-ìyísódì: *kò/ò, kì, máà/má.* Fọ́nrán kejì ni ọ̀rọ̀-ìṣe àfarahẹ ìbẹ̀rẹ̀, àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tí kò lè dá dúró tí wọ́n sì máa ń ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe kíkún. Àpẹẹrẹ wọn ni: *dá, tún, bá, fi, fẹ́rẹ̀, ní.* Fọ́nrán kẹta ni ọ̀rọ̀-ìṣe kíkún, ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó lè dá dúró gẹ́gẹ́ bí kókó gbólóhùn. Ọ̀rọ̀-ìṣe afarahẹ ìparí ni fọ́nrán kẹrin, àwọn náà kò lè dá dùró wọ́n sì máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe kíkún. Àpẹẹrẹ wọn ni *ka, dè* gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe jẹ yọ nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí

Olú gbé ẹrù *ka* orí. Dúró *dè* mi.

Agbẹ̀yìn ọ̀rọ̀-ìṣe ni fọ́nrán karùn-ún nínú ìhun àpólà ìṣe, wọ́n máa ń ṣe àfikún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe kíkún, àpẹẹrẹ wọn ni *rí, nà, mọ̀, rárá, sá.*

## Àsọlé/Àríwísí

Púpọ̀ nínú àwọn fọ́nrán àpólà ìṣe tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Ayọ Bamgboṣe yà sọ́tọ̀ kìí ṣe ara ìhun àpólà ìṣe. Fún àpẹẹrẹ, atọ́ka ìbá-ìṣẹ̀lẹ̀ ni *ń* tí wọ́n pè ní ẹ̀rún ọ̀rọ̀-ìṣe, atọ́ka àsìkò ọjọ̀-iwájú ni *yóò/yó/ó, á, máa/ma,* àti *a* tí wọ́n pè ní aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aláìbárarìn. Bákan náà atọ́ka ìyísódì *kò/ò, kì* àti *máà/má* kìí ṣe ara ìhun àpólà ìṣe rárá. Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀, àsìkò àti ìyísódì jẹ́ ìsọ̀rí gírámà aláìnítumọ̀ àdámọ́ tí a kó papọ̀ sí àpólà apàrísídà (APAPR) tí ó máa ń jẹ yọ ṣáájú àpólà ìṣe nínú ẹ̀hun. Fún ìdí èyí, a kò ní kà wọ́n mọ́ ara ìhun àpólà ìṣe nínú bébà yìí.

Yàtọ̀ sí èyí, a máa fi hàn pé àwọn fọ́nrán yòókù tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Bamgboṣe yà sọ́tọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún tí ó ń ṣe àfikún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú ìhun àpólà ìṣe. Ìwọ̀fún ni

[1] Àrokò APIṢ dúró fún Àpólà Ìṣe. Àwọn àrokò mìíràn ti a lò nínù bébà yìí ni ìwọ̀nyí: *APAPR = Àpólà Apàrísídà, APAT = Àpólà Atọ́kùn, APEP = Àpólà Aṣẹ̀pọ́n, APOR = Àpólà Orúkọ, AT = Ọ̀rọ̀ Atọ́kùn, EP = Ọ̀rọ̀ Aṣẹ̀pọ́n, IṢ = Ọ̀rọ̀ Ìṣe, o.i. = ojú ìwé, # = ààlà gbólóhùn, ( ) = àkámọ́ afìwọ̀fún-hàn* àti *--- = àmì ìṣófo.*

àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún wọ̀nyí sì jẹ̀ fún ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe. Ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí yìí ni wọ́n pé ní ọ̀rọ̀-ìṣe kíkún.

Àwọn fọ́nrán àpólà ìṣe kan tún wà tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Bamgboṣe kò mẹ́nu bà. Àwọn ni àmúpé àti àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe[2]. Iṣẹ́ àmúpé ni àwọn ẹ̀pọ́n méjèèjì máa ń ṣe fún ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàmúpé wọ̀nyí gbọ́dọ̀ jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí bẹ́ẹ̀ pé Àwọn wọ̀nyí ni mo yà sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe nínú bébà yìí.

**Awóbùlúyì (1972, 1978 àti 2013)**

Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Ọladele Awobuluyi kò ya àpólà ìṣe sọ́tọ̀ láti ṣàlàyé ìhun rẹ̀ tàbí láti fún un ní oríkì. Àmọ́ ṣá, wọ́n ṣàlàyé àwọn àpọ́nlé tí a máa ń ṣàmúlò láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ẹ̀hun. Awobuluyi (1978, o.i. 68-78; 2013, o.i. 142-167) ya àwọn àpọ́nlé ọ̀rọ̀-ìṣe/àpólà ìṣe wọ̀nyí sọ́tọ̀: àpọ́nlé aṣáájú-ìṣe, aṣàpọ́nlé aṣáájú-ìṣe, àpọ́nlé atẹ̀lé-ìṣe àti aṣàpọ́nlé atẹ̀lé-ìṣe, Àwọn àpọ́nlé aṣáájú-ìṣe ni ìwọ̀nyí sílébù olóhùn òkè *ó/ø,* àsìkò ọjọ́-iwájú *yóò/óò, á, ó máa, níí,* ibá-ìṣẹ̀lẹ̀: *a, ń, máa, ti, tíì,* ìyísódì: *kì/ì, kò/ò, máà, má,* àti atọka *kání bá, baà/ba, báà.* Àwọn àpọ́nlé aṣáájú-ìṣe tí ó kù ni *jẹ́, ṣe, wá, lè, sì, dẹ̀, mà, kàn, tún, jọ/jìjọ/dìjọ, kọ́/kọ̀kọ́, nìkan, pàpà, gbọ́dọ̀, tètè, dédé, kúkú, ṣẹ̀ṣẹ̀, kúkú, jàjà, mọ̀ọ́mọ̀, dìídì, tiẹ̀/tilẹ̀, wulẹ̀, túnbọ̀/túbọ̀, ṣáà/sáà, sábà.* Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Awobuluyi ni irú-wá-ògìrì-wá ní àwọn àpọ́nlé aṣáájú-ìṣe wọ̀nyí, ṣùgbọ́n màá fi hàn láìpẹ́ pé bẹ́ẹ̀ kọ́ ni ọ̀rọ̀ rí.

Yàtọ̀ sí àwọn àpọ́nlé aṣáájú-ìṣe òkè wọ̀nyí, Awobuluyi (2013, o.i. 155-159) ya àwọn aṣàpọ́nlé aṣáájú-ìṣe sọ́tọ̀. Àwọn ni aṣàpọ́nlé aṣáájú-ìṣe alátọ́kùn tí mo kọ ní àkọhàn-dẹ̀gbẹ́ ní àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

Oyè é *bá mi* mú un bọ̀.
Oyè é *fi eyín* gé e.
Oyè é *ti Èkó* wá (Awobuluyi, 2013, o.i. 156)

Àpẹẹrẹ aṣàpọ́nlé aṣáájú-ìṣe mìíràn ni àwọn àpólà ìṣe aṣàpọ́nlé aṣáájú-ìṣe tí mo kọ ní àkọhàn-dẹ̀gbẹ́ ní àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

Àbí ọtí ti *sáré* tán.
Oúnjẹ ti *yára* tán. (Awobuluyi, 2013, o.i. 158)

Àwọn aṣàpọ́nlé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe ni aṣàpọ́nlé alátọ́kùn atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe tí *pẹ̀lú, fún, sí* àti *ní* máa ń bẹ̀rẹ̀ wọn. Àwọn àpẹẹrẹ wọn ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

Olè náà máa dé àgọ́ ọlọ́pàá *pẹ̀lú túlàsì.*
Ẹ pe ọmọ náà *fún mi.*
Wọ́n péjọ *sí ojúde ọba.*
Mo rí irú aṣọ yìí *ní ọjà*[3].

[2] Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Bamgboṣe ṣàlàyé pé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kan máa ń gba àbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àbùdá àdámọ́ wọn, ṣùgbọ́n wọn kò ka àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe mọ́ ara fọ́nrán àpólá ìṣe (Bamgboṣe, 1967, o.i.22-23)

[3] Nínú Awobuluyi (2013, o.i. 160, 161,162 & 164) ni a ti mú àpẹẹrẹ wọ̀nyí jáde.

Àwọn aṣàpọ́nlé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe mìíràn ni aṣàpọ́nlé aláìlátọ́kùn atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe, bíi ọ̀rọ̀-orúkọ/àpólà orúkọ àti odidi gbólóhùn, àti àpọ́nlé ẹléyọ-ọ̀rọ̀ atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe. Àpẹẹrẹ wọn ni mo kọ ni àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

Ẹ é lọ *ire (*lọọ*re)* (ọ̀rọ̀-orúkọ)
Ṣe é *bí mo ti wí* (àpólà orúkọ)
A ti jọ ń fa ọ̀rọ̀ yìí bọ̀ *(ó) ti pẹ́* (odidi gbólóhùn)
Ohun tí a ti ń wí nìyí *ó ju ogún ọdún* (odidi gbólóhùn) (Awobuluyi, 2013, o.i. 166)

Àpẹẹrẹ àpọ́nlé ẹléyọ-ọ̀rọ̀ atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe ni *mọ́, rí, ṣáá, rárá, gan-an, púpọ̀, jáì, lọ* àti *tán.*

Kinní ọ̀ún burú *gan-an/púpọ̀/jáì.*
Mo mú u dání *ṣáá,* a kì í mọ̀
Òjó kò wá *mọ́/rárá* níjọ́ yẹn.
Òjó ti wòran *lọ.*
Mo ti dé ilé *tán* kí òjò náà tó bẹ̀rẹ̀, Mo dé Èkó *rí.* (Awobuluyi, 2013, o.i.167)

## Àsọlé/Àríwísí

Àwọn fọ́nrán tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Awobuluyi pé ní àpọ́nlé ni a pé ní ẹ̀pọ́n nínú bébà yìí. A gbọ́dọ̀ pe àkíyèsí síi pé púpọ̀ nínú àwọn fọ́nrán tí wọ́n yà sọ́tọ̀ ni wọ́n ṣisẹ́ ẹ̀pọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe. Àmọ́ ṣáá, a rí àwọn fọ́nrán kan tí kìí ṣe ara ìhun àpólà ìṣe tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Awobuluyi kó pọ̀ mọ́ àpólà ìṣe. Àwọn ni ìwọ̀nyí: sílébù olóhùn òkè *ó/ø,* àsìkò ọjọ́-iwájú *yóò/óò, á, ó máa, níí,* ibá-ìṣẹ̀lẹ̀: *a, ń, máa, ti, tíì,* ìyísódì: *kì/ì, kò/ò, máà, má* àti atọka *kání bá, baà/ba, báà.* Ara ìhun àpólà apàrísídà (APAPR) ni àwọn fọ́nrán wọ̀nyí jẹ́. Fọ́nrán tí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Awobuluyi pè ní àpólà ìṣe aṣàpọ́nlé aṣáájú-ìṣe kìí ṣe bẹ́ẹ̀ rárá, a máa fi hàn nínú àlàyé àti ìtúpalẹ̀ mi láìpẹ́ pé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) ni wọ́n jẹ́, wọn kìí ṣe àpólà ìṣe.

## Àfojúsùn Bébà yìí

Nínú bébà yìí, a máa ṣàgbéyẹ̀wò ìhun àpólà ìṣe èdè Yorùbá láti lè ṣàmújáde àwọn ẹ̀pọ́n ninú àpólà ìṣe àti ipa tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn kó nínú ìhun àpólà ìṣe èdè Yorùbá. A máa ṣe èyì nìpa fífún àpólà ìṣe èdè Yorùbá ní oríkì, a máa fún ẹ̀pọ́n ní oríkì bákan náà. A óò ṣàlàyé oríṣi ẹ̀pọ́n méjì tí ó wà nínú ìhun àpólà ìṣe, ẹ̀pọ́n aṣàfikún àti ẹ̀pọ́n aṣàmúpé, àti ipa tí ọ̀kọ̀ọ̀kan ń kó nínú ìhun àpọlà ìṣe.

## Oríkì

Àpólà ìṣe ni *ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àsópọ̀ ọ̀rọ̀ tí ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ orí rẹ̀ tí a sì a lè lò gẹ́gẹ́ bí kókó gbólóhùn nínú gbólóhùn aṣeégbà.* Oríkì yìí fi hàn pé ọ̀rọ̀-ìṣe kan ni o máa ń wà ní àpólà ìṣe. Táíwò (2018b) ki ọ̀rọ̀-ìṣe gẹ́gẹ́ bí *ọ̀rọ̀ tí ó lè dá wà tàbí tí ó gba ẹ̀pọ́n nínú àpólà ìṣe*[4]. Bí a bá rí àpólà

[4] Bamgboṣe (1972a, o.i.13-13, 1990, o.i.132) ki ọ̀rọ̀-ìṣe báyìí
*Ọ̀rọ̀ tí ó bá lè jẹ yọ nínú férémù #APOR ___ (APOR)# jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe.*
*Bí a bá rí ọ̀rọ̀ mìíràn tí wọ́n fara jọ ọ̀rọ̀-ìṣe ṣùgbọ́n tí wọn kò lè jẹ*

ìṣe tí ó ní ju ọ̀rọ̀-ìṣe kan lọ, irú àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀ kìí ṣe àpólà ìṣe kan rárá, ó ti ju àpólà ìṣe kan lọ. Èyí fi hàn pé iye ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó bá wà nínú ìhun àpólà ìṣe ni a fi máa mọ iye àpólà ìṣe ti a ń sọ nípa rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:

a. Olú [*ra* ìwé].
Ọ̀gá wa [*jẹ* oúnjẹ náà].
Olùkọ́ náà [*kóríìra* ọ̀lẹ].
Ọmọ mi [*fẹ́ràn* bàtà yìí].
Adìẹ wa ti [*yé* ẹyin]
Wọ́n [*ta* òṣì ní àdúgbò yẹn]

b. Ọmọ náà [*lọ*].
Bàbá àgbà ti [*kú*]

Ọ̀rọ̀-ìṣe kan, tí a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́, ni ó wà nínú àwọn gbólóhùn tí ó wà ní àpẹẹrẹ (a) lókè, ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sì gba àpólà orúkọ gẹ́gẹ́ bí àbọ̀ nítorí wọ́n jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀. Àmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó wà ní àwọn àpẹẹrẹ (b) jẹ́ aláígbàbọ̀, kò sí apólà orúkọ tí ó jẹ yọ tẹ̀lé wọn. Ní àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ (a), àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe àti àbọ̀ wọn ni wọ́n papọ̀ jẹ́ àpólà ìṣe, àwọn ni a sì fi sínú àkámọ́. Ọ̀rọ̀-ìṣe nìkan ni àpólà ìṣe ní àwọn àpẹẹrẹ gbólóhùn méjèèjì tí ó wà ní (b), àwọn náà ni a sì fi sínú àkámọ́ pẹ̀lú.

Ní àwọn gbólóhùn tí ó wà ní àpẹẹrẹ (d) dé (ẹ) ní ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, àpólà ìṣe ni a fi sínú àkámọ́, tí a sì kọ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọn ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyí kò lè dá wà láìgba àwọn wúnrẹ̀n tí ó tẹ̀lé wọn tí wọ́n papọ̀ jẹ́ àpólà ìṣe. Àwọn wúnrẹ̀n wọ̀nyí ni a mọ̀ sí *àmúpé*[5]. Ní àwọn gbólóhùn méjèèjì tí ó wà ní àpẹẹrẹ (d), àpólà orúkọ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n ni àmúpé. Ní àwọn gbólóhùn mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí ó wà ní àpẹẹrẹ (e) àti gbólóhùn mẹ́ta tí ó wà ní àpẹẹrẹ (ẹ), àpólà aṣẹ̀pọ́n nìkan ni àmúpé.

d. Obìnrin náà [*fi* owó sí àpò].
Ẹṣin náà [*ta* olówó rẹ̀ ní ìpá].

e. Àpapọ̀ owó náà [*kú* sí múrí mẹ́wàá].
Wàhálà rẹ̀ [*já* sí asán].
Ìyá àgbà n [*gbé* ní Mọ́níyà].
Wàhálà rẹ́ kò [*mọ* ní kékeré].

ẹ. Ọbẹ̀ náà [*ta* sansan].
Aṣọ náà [*bẹ́* yòò].
Ọmọ náà [*já* fáfá].

Ọ̀rọ̀-ìṣe nìkan ni ó wà ní àwọn àpẹẹrẹ (f) ní ìsàlẹ̀ wọ̀nyì, àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyí sì ni àpólà ìṣe, àwọn náà ni ó jẹ́ odindi gbólóhùn gẹ́gẹ́ bí a ṣe mẹ́nu bà á ṣáájú.

f. [*jọ̀ọ́*] [*dákun*] [*ṣọ́ra*] [*káre*]

*yọ nínú férémù yìí, a gbọ́dọ̀ kà wọ́n sí kòbẹ́gbẹ́mu*

.

Taiwo (2018b, o.í.5-8) ṣàlàyé lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ àbùkù lílo férémù láti fún ọ̀rọ̀-ìṣe ní oríkì kí ó tó wá dábàá oríkì tuntun fún ọ̀rọ̀-ìṣe èdè Yorùbá.

[5] Táíwò (2018a) ṣàlàyé àwọn òṣùwọ̀n tí a lè fí dá ọ̀rọ̀-ìṣe mọ̀ ní èdè Yorùbá.

Bí gbólóhùn bá jẹ́ kìkì àpólà ìṣe (tàbí kìkì ọ̀rọ̀-ìṣe) bí irú àwọn tí wọ́n wà ní àpẹẹrẹ (f) lókè, gbólóhùn bẹ́ẹ̀ ni a ń pè ní gbólóhùn àṣẹ, gbólóhùn ẹ̀bẹ̀ tàbí gbólóhùn èékí (gbólóhùn ìkíni).

Ní àwọn àpẹẹrẹ (g), ọ̀rọ̀-ìṣe méjì méjì ní ó wà ní àpẹẹrẹ méjì àkọ́kọ́, èyí sì túmọ̀ sí pé àpólà ìṣe méjì méjì (tàbí odindi gbólóhùn méjì méjì) ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn jẹ́ pẹ̀lú. Ọ̀rọ̀-ìṣe méta ní ó wà ní àpẹẹrẹ kẹta, ọ̀kan nínú wọn, ìyẹn ọ̀rọ̀-ìṣe àkọ́kọ́, *rà*, gba àbọ̀ nítorí pé ọ̀rọ̀-ìṣe agbàbọ̀ ní.

g. [*Sáré*][*wá*]
[*dìde*][*jẹun*]
[*ra* iṣu] [*sè*] [jẹ]

Ó ṣe é ṣe láti ṣe ìtúpalẹ̀ gbólóhùn tí ó wà ní àpẹẹrẹ (g) gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣe ní ìsàlẹ̀ yìí.

[*Sáré*][*wá*] → [*Sáré*]; [*wá*]
[*dìde*][*jẹun*] → [*dìde*]; [*jẹun*]
[*ra* iṣu] [*sè*] [jẹ] → [*ra* iṣu]; [*se* iṣu]; [*jẹ* iṣu]

Ìtúpalẹ̀ tí a ṣe lókè yìí jẹ́ kí iye àpólà ìṣe tí *[ra iṣu] [se] [jẹ]* hànde.

Ní gbólóhùn tí ó wà ní àpẹẹrẹ (gb) ní ìsàlẹ̀ yìí, ọ̀rọ̀-ìṣe márùn-ún ní ó wà nínú gbólóhùn náà. Èyí fi hàn pé àpólà ìṣe márùn-ún ni gbólóhùn ọ̀hún ni gẹ́gẹ́ bí mo ṣe fi ọ̀kọ̀ọ̀kan sínú àkámọ́.

gb. Ọláolúwa [*sáré*] [*lọ*] [*ra* ẹran] [*pa*] [*tà*]

Láti fi hàn pé àpólà ìṣe márùn-ún ni ó wà nínú àpẹẹrẹ (gb) lókè, a lè ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ sí márùn-ún báyìí.

Ọláolúwa [*sáré*] [*lọ*] [*ra* ẹran] [*pa*] [*tà*]
→ Ọláolúwa [*sáré* ←*sá eré*]
→ Ọláolúwa [*lọ*]
→ Ọláolúwa [*ra* ẹran]
→ Ọláolúwa [*pa* ẹran]
→ Ọláolúwa [*ta* ẹran]

Àpólà ìṣe tí ó wà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn gbólóhùn márùn-ún ni a fi sínú àkámọ́.

Àwọn gbólóhùn tí wọ́n bá ní ju ọ̀rọ̀-ìṣe kan lọ gẹ́gẹ́ bí àwọn tí wọ́n wà ní àpẹẹrẹ (g) àti (gb) ni a ń pè ní gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe àsínpọ̀.

Ní àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe àfibọ̀ tàbí gbólóhùn onìbọ̀ ni a máa ń pè wọ́n.

Ọmọ tí mo *rí* lánàá *sanra* púpọ̀.
Ọkùnrin tí a ń *sọ* nípa rẹ̀ *wà* ní àdúgbò wa.

Ọ̀rọ̀-ìṣe méjì méjì ni ó wà nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn àpẹẹrẹ méjèèjì òkè yìí, àwọn ni a sì kọ ni àkọhàn-adẹ̀gbẹ́. Èyí tún fi hàn pé gbólóhùn méjì méjì ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ń ṣe. Ìtúpalẹ̀ àwọn gbólóhùn méjèèjì, gẹ́gẹ́ bí àlàyé wa ṣe fi hàn, ni a ṣe ní ìsàlẹ̀ yìí.

Ọmọ tí mo [*rí* lánàá] [*sanra* púpọ̀].
→ Ọmọ [*sanra* púpọ̀].
→ Mo [*rí* ọmọ lánàá].

Ọkùnrin tí a ń [*sọ* nípa rẹ̀] [*wà* ní àdúgbò wa].
→ Ọkùnrin [*wà* ní àdúgbò wa].
→ A ń [*sọ* nípa ọkùnrin].

Bí a ṣe ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn gbólóhùn méjèèjì lókè jẹ́ kí ó hàn gbangba pé gbólóhùn méjì méjì ni ọ̀kọ̀ọ̀kan wọ́n ní.

## Ìhun Àpólà Ìṣe

Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a lè pín ìhun àpólà ìṣe sí, àwọn ni orí àti ẹ̀pọ́n. Ọ̀rọ̀-ìṣe ni orí nínú ìhun àpólà ìṣe, ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ méjì ni a sì lè lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n. Àwọn ni àpólà aṣẹ̀pọ́n àti àpólà orúkọ. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti mọ̀, orí nìkan ni ó jẹ́ kànńpá nínú ìhun àpólà ìṣe, ìwọ̀fún ni ẹ̀pọ́n jẹ́. Ìhun àpólà ìṣe ni a fi hàn ní àtẹ ìsàlẹ̀ yìí.




A óò tẹ̀síwájú báyìí láti ṣàgbéyẹ̀wò àwọn ẹ̀pọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe.

## Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hànde ní àtẹ òkè yìí, òrìṣi ẹ̀pọ́n méjì ni a lè yà sọ́tọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe. Àwọn ni èyí tí ó máa ń jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, tí a ń pè ní ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, àti èyí tí ó máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe tí a ń pè ní ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí.

Ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni a mọ̀ sí ẹ̀pọ́n aṣàfikún, àwọn sì ni a mọ̀ sí àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP). A lè pín ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí sí méjì, àwọn ní ẹ̀pọ́n aṣàmúpé àti aṣàfikún. Àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe ni àpólà orúkọ àbọ̀ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n. Àpólà aṣẹ̀pọ́n náà ni a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí aṣàfikún nínú ìhun àpólà ìṣe.

## Oríkì àti Àbùdá Ẹ̀pọ́n

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé ṣáájú, ìwọ̀fún ni ẹ̀pọ́n jẹ́ nínú ìhun àpólà ìṣe. Àmọ́ bí ó ti jẹ́ ìwọ̀fún yìí, ipa pàtàkì ni ó ń kó nínú ìhun àpólà ìṣe, bẹ́ẹ̀ sì ni ó ní àwọn àbùdá tí a lè fi dá a mọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe. Kí a tó ṣàgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá wọ̀nyí, mo máa kọ́kọ́ fún ẹ̀pọ́n ní oríkì.

A lè ki ẹ̀pọ́n gẹ́gẹ́ bí *ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí a lò nínú ìhun àpólà ìṣe láti ṣe òdiwọ̀n ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nìpa mímú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé tàbí nípa fífi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí.* Oríkì yìí fi hàn pé a máa ń lo àwọn ẹ̀pọ́n kan láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé. Láìsí irú àwọn ẹ̀pọ́n bẹ́ẹ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe, ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kò ní pé, irú gbólóhùn tàbí ìsọ bẹ́ẹ̀ kò ní ṣe é gbà tàbí kí ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ sí ohun tí a ní lọ́kàn. A sì máa ń lo àwọn ẹ̀pọ́n kan láti ṣe àfikún sí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú ìhun àpólà ìṣe. Bí a lo irú àwọn ẹ̀pọ́n yìí tàbí a kò lò wọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe kò lé yí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí padà, bẹ́ẹ̀ sì ni kò lè sọ gbólóhùn náà di àìṣeégbà.

Bí a bá tẹ̀lé ìjíròrò àti àlàyé òkè wọ̀nyí, a lè ṣàmújáde àwọn àbùdá tí a lè fi dá àwọn ẹ̀pọ́n mọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe. Àwọn àbùdá náà ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

- Ẹ̀pọ́n lè jẹ́ aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí.
- Ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí máa ń fi kún ìtúmọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń pọ́n.
- Ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí lè fi kún ìtúmọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí kí ó mú ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé. Ìyẹn ni pé, oríṣi ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe méjì ni a lè yà sọ́tọ̀, àwọn ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe àti ẹ̀pọ́n aṣàmúpé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe.
- A lè yọ ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kúrò nínú ìhun àpólà ìṣe nínú gbólóhùn láìmú kí gbólóhùn náà di àìṣeégbà, nítorí pé ìwọ̀fún aṣàfikún ni ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ fún ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe.
- Bákan náà, a lè yọ ẹ̀pọ́n aṣàfikùn atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kúrò nínú ìhun àpólà ìṣe nítorí pé ìwọ̀fún ní òun náà jẹ́ pẹ̀lú.
- Ṣùgbọ́n kò ṣe é ṣe kí a yọ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kúrò nínú ìhun àpólà ìṣe nítorí kànńpá ni ó jẹ́ fún ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe.
- Bí a bá yọ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kúrò nínú ìhun àpólà ìṣe, gbólóhùn náà kò ní ṣe é gbà tàbí kí ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ sí ohun tí a ní lọ́kan.
- Ò ṣé é ṣe kí ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí méjì jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn nínú ìhun àpólà ìṣe, ṣùgbọ́n kò ṣe é ṣe kí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn nínú ìhun àpólà ìṣe.

Ní báyìí, a óò tẹ̀síwájú láti jíròrò lórí àwọn ẹ̀pọ́n, a óò sì ṣàlàyé wọn pẹ̀lú àpẹẹrẹ gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ láti lè jẹ́ kí a lè dá wọn mọ̀ nínú ẹ̀hun èdè Yorùbá.

## Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

Ẹ̀pọ́n aṣàfikún jẹ́ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí ó ń ṣàlàyé nípa ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń pọ́n nínú àpólà ìṣe. Irú àlàyé yìí ni láti sọ ìwọ̀nba ìtumọ̀ tí a gbọ́dọ̀ fún ọ̀rọ̀-ìṣe tí àfikún ń pọ́n.

Oríkì yìí fi hàn pé ọ̀kan náà ni iṣẹ́ tí ẹ̀pọ́n aṣàfikún nínú àpólà ìṣe àti èyí tí ẹ̀yán nínú àpólà orúkọ ń ṣe. Á jẹ́ pé ọ̀kan náà ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún àti ẹ̀yán ń ṣe nítorí pé iṣẹ́ kan náà ni wọ́n ń ṣe nínú ẹ̀hun, ṣùgbọ́n ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí àwọn méjèèjì ń bá ṣiṣẹ́ pọ̀ ni ó yàtọ̀. Ẹ̀pọ́n aṣàfikún ń bá ọ̀rọ̀-ìṣe ṣiṣẹ́ pọ̀, ó sì ń pọ́n ọn nínú ẹ̀hun, àmọ́ ẹ̀yán ń bá ọ̀rọ̀-orúkọ ṣiṣẹ́ pọ̀ nípa yíyán an nínú ẹ̀hun.

Ní báyìí, a máa tẹ̀síwájú láti ṣàlàyé oríṣi ẹ̀pọ́n aṣàfikún méjì tí mo yà sọ́tọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe. Àwọn ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe àti ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe.

## Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Íṣe

Ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe ni àwọn aṣàfikún tí ó máa ń jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpólà ìṣe. Ó ṣe é ṣe kí ẹ̀pọ́n aṣàfikún irú èyí ju ẹyọ kan lọ. Ìyẹn ni pé, ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe lè jẹ́ ẹyọ kan, méjì, tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mẹ́nu bà á ṣáájú, àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) ni ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ ti a sábà máa ń lò láti pọ́n ọ̀rọ̀-íṣe tí ó sì máa ń jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń pọ́n. Àwọn àpẹẹrẹ ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe ni a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí[6].

| | |
|---|---|
| O *jẹ́* sáré lọ ra tìrẹ. | Ọmọ náà *ṣe* sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. |
| Mo *lè* ṣe báyìí dọ̀la. | Wọ́n ti *bábá* ṣe ìpinnu náà. |
| Omidan náà *wá* mọ ọ̀rọ̀ ọ́ sọ lójú rẹ. | Mo dọ̀bálẹ̀, mo *sì* kí bàbá wa. |
| Wọ́n *mà* wáà. | Kò *lè nìkan* gbé ẹrù yẹn. |
| A *jọ/jìjọ* sọ̀rọ̀ ní ẹ̀kan náà. | Ẹ *kàn* dákẹ́ ṣá. |
| Wọ́n *tún* pariwo sí i. | Mo ti *kọ́kọ́* gbọ́ ariwo wọn. |
| Ẹ *pàpà* fi ìyà jẹ ẹ́. | O *gbọ́dọ̀ tètè* parí iṣẹ́ yẹn. |
| Wọ́n *kúkú* sọ bẹ́ẹ̀. | Mo *kàn dédé* gbọ́ tí wọ́n ń kan ilẹ̀kùn |
| O *ṣẹ̀ṣẹ̀* fèsì látàárọ̀. | Ọpẹ́ o, ẹ *jàjà* wá lónìí! |
| Wọ́n *mọ̀ọ́mọ̀* dá ìjà sílẹ̀. | Ẹ máà *wulẹ̀* pè é, kò ní yọjú. |
| Mo *tiẹ̀/tilẹ̀* ka ìwé ọ̀hún. | Ọkùnrin náà kìí *sábà* gba ibí kọjá. |
| Obìnrin náà *túbọ̀* tẹsẹ̀ mọ́ ìrìn rẹ̀. | Olú kò *ṣáà* fẹ́ẹ́ gbọ́ ìkìlọ̀. |

Àpólà aṣẹ̀pọ́n (tàbí ọ̀rọ̀ aṣẹ̀pọ́n) ni àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún tí a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí. Àfikún ni wọ́n ń ṣe sí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tí wọ́n ń pọ́n, fún ìdí èyí, ìwọ̀fún ni wọ́n nínú ẹ̀hun tí wọ́n ti jẹ yọ, kìí ṣe kàǹpá gẹ́gẹ́ bí mo ṣe sọ ṣáájú.

Bí a bá yọ wọ́n kúrò nínú ẹ̀hun tí wọ́n ti jẹ yọ, ẹ̀hun ọ̀hún ṣì máa ṣe é gbà gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣe nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | |
|---|---|
| O sáré lọ ra tìrẹ . | Ọmọ náà sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. |
| Mo ṣe báyìí dọ̀la. | Wọ́n ti ṣe ìpinnu náà. |
| Omidan náà mọ ọ̀rọ̀ ọ́ sọ lójú rẹ. | Mo dọ̀bálẹ̀, mo kí bàbá wa. |
| Wọ́n wáà. | Kò gbé ẹrù yẹn. |
| A sọ̀rọ̀ ní ẹ̀kan náà. | Ẹ dákẹ́ ṣá. |
| Wọ́n pariwo sí i. | Mo ti gbọ́ ariwo wọn. |
| Ẹ fi ìyà jẹ ẹ́. | O parí iṣẹ́ yẹn. |
| Wọ́n sọ bẹ́ẹ̀. | Mo gbọ́ tí wọ́n ń kan ilẹ̀kùn |
| O fèsì látàárọ̀. | Ọpẹ́ o, ẹ wá lónìí! |
| Wọ́n dá ìjà sílẹ̀. | Ẹ máà pè é, kò ní yọjú. |
| Mo ka ìwé ọ̀hún. | Ọkùnrin náà kìí gba ibí kọjá. |
| Obìnrin náà tẹsẹ̀ mọ́ ìrìn rẹ̀. | Olú kò fẹ́ẹ́ gbọ́ ìkìlọ̀. |

Ní ìgbà mìíràn, à máa ń gbé àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún kan kúrò ní àyè wọn ní ibi tí wọ́n ti ń pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe lọ sí iwájú láti ṣe ìtẹnumọ́ fún àpólà orúkọ. Eléyìí máa ń wáyé bí a bá kọ́kọ́ ṣe ìtẹnumọ́

[6] Wo Awobuluyi (2013, o.i. 143-145, 154-159) fún àpẹẹrẹ àti àlàyé sí i lórí àwọn ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe tí wọ́n pè ní àpọ́nlé aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe.

fún irú àpólà orúkọ bẹ̀ẹ̀ nípa gbígbé e wá síwájú, tí atọ́ka gbólóhùn ìtẹnumọ́ tí i ṣe *ni* sì tẹ̀lé e. Àlàyé wa yìí fojú hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí.

Mo *sì* kí bàbá wa.
i) Bàbá wa ni mo *sì* kí. → ii) Bàbá wa *sì* ni mo - kí.

A gbé àpólà orúkọ *bàbá wa,* tí ó jẹ́ àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe *kí,* wá sí iwájú, atọ́ka ìtẹnumọ́, ìyẹn *ni,* sì tẹ̀lé e nì àpẹẹrẹ (i), ṣùgbọ́n ní àpẹẹrẹ (ii), a gbé ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe *sì* wá síwájú, ó sì jẹ yọ tẹ̀lé àpólà orúkọ *bàbá wa* tí a tẹnu mọ́, àyè tí ó wà tẹ́lẹ̀ sì ṣófo.

Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe mìíràn tí a tún lè gbé kúrò ní àyè wọn wá sí iwájú tẹ̀lé àpólà orúkọ ni wọ́n wà ní àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

A *jọ/jìjọ* sọ̀rọ̀ ní ẹ̀kan náà.
[Ní] Ẹ̀kan náà ni a *jọ/jìjọ* sọ̀rọ̀ → [Ní] Ẹ̀kan náà *jọ/jìjọ* ni a - sọ̀rọ̀

Wọ́n *tún* pariwo síi.
Ariwo ni wọ́n *tún* pa síi. → Ariwo *tún* ni wọ́n - pa síi.

Mo ti *kọ́kọ́* gbọ́ ariwo wọn.
Ariwo wọn ni mo ti *kọ́kọ́* gbọ́. → Ariwo wọn *kọ́kọ́* ni mo ti - gbọ́.

Ẹ *pàpà* fi ìyà jẹ ẹ́.
Ìyà ni ẹ *pàpà* fi jẹ ẹ́ → Ìyà *pàpà* ni ẹ - fi jẹ ẹ́

Wọ́n *kúkú* sọ bẹ́ẹ̀.
Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n *kúká* sọ → Bẹ́ẹ̀ *kúká* ni wọ́n - sọ

Mo *tiẹ̀/tilẹ̀* ka ìwé ọ̀hún.
Ìwé ọ̀hún ni mo *tiẹ̀/tilẹ̀* kà. → Ìwé ọ̀hún *tiẹ̀/tilẹ̀* ni mo - kà.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣáájú, ọ ṣe é ṣe kí àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn nínú ìhun àpólà ìṣe. Ò dàbí ẹni pé ìjẹyọpọ̀ àwọn àfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe kò tẹ̀lé òfin kankan bí kò ṣe irú ìtumọ̀ tí a bá fẹ́ gbé jáde.

Àpẹẹrẹ bí àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe méjì tàbí mẹ́ta ṣe jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpólà ìṣe ní wọ́n wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

O *jẹ́ tètè* sáré lọ ra tìrẹ .
Mo *lè kúkú* ṣe báyìí dọ̀la.
Wọ́n *mà lè tètè* wáà.
Ẹ *kàn dédé* dákẹ́ ṣá.
O *gbọ́dọ̀ tètè* parí iṣẹ́ yẹn.
Mo *tiẹ̀/tilẹ̀ mọ̀ọ́mọ̀* ka ìwé ọ̀hún.

Ọmọ náà *tiẹ̀ ṣe* sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀.
Mo *kúkú lè* ṣe báyìí dọ̀la.
Kò *tiẹ̀ lè nìkan* gbé ẹrù yẹn.
Wọ́n *pàpà tún* pariwo síi.
Mo *kàn dédé* gbọ́ tí wọ́n ń kan ilẹ̀kùn
Obìnrin náà *wà túbọ̀* tẹsẹ̀ mọ́ ìrìn rẹ̀.

Àwọn wúnrẹ̀n kan wà tí a lè pè ní ọ̀rọ̀-ìṣe bí wọ́n bá dá wà, ìyẹn láìjẹ́ pé a lò wọ́n nínú ẹ̀hun, ṣùgbọ́n a máa ń lo irú àwọn wúnrẹ̀n bẹ́ẹ̀ láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe. Àpẹẹrẹ wọn ni ó wà nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, àwọn ni a sì kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́.

Ọmọ náà *sáré* dàgbà
Ó *yára* gun igi
Ọbẹ̀ náà *dùn* tó

Adé sùn *lọ.*
Oúnjẹ tí a rà lánàá ti *sáré* tán
Èso náà *sáré* hù.

Ní àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, *sáré* pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe *dàgbà; lọ* pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe *sùn; yára* pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe *gùn; sáré* pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe *tán; tó* pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe *dùn; sáré* sì pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe *hù*. Bí a bá yọ àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ń pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe wọ̀nyí kúrò, ọ̀rọ̀-ìṣe kan ló kù nínú ẹ̀hun tàbí gbólóhùn kọ̀ọ̀kan.

| | |
|---|---|
| Ọmọ náà *dàgbà* | Adé *sùn*. |
| Ó *gun* igi | Oúnjẹ tí a rà lánàá ti *tán* |
| Ọbẹ̀ náà *dùn*. | Èso náà *hù* |

Láti fi hàn pé àwọn ọ̀rọ̀-aṣàfikún wọ̀nyí kìí ṣe ọ̀rọ̀-ìṣe, ó ṣeé ṣe kí a fi ọ̀rọ̀-aṣàfikún mìíràn, ìyẹn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n, rọ́pò wọn ní ọ̀gangan àyè tí wọ́n ti jẹ yọ láìsí ìyípadà nínú ìtumọ̀ rárá. Ní àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, a fi ẹ̀pọ́n aṣàfikún mìíràn rọ́pò àwọn aṣàfikún wọ̀nyí.

| | |
|---|---|
| Ọmọ náà *sáré* dàgbà | Ọmọ náà *tètè* dàgbà |
| Adé sùn *lọ*. | Adé sùn *fọnfọn*. |
| Ó *yára* gun igi | Ó *tètè* gun igi/ Ó gun igi *kìàkìà* |
| Oúnjẹ tí a rà lánàá ti sáré *tán* | Oúnjẹ tí a rà lánàá ti *tètè* tán/tán *kíákíá* |
| Ọbẹ̀ náà *dùn* tó | Ọbẹ̀ náà dùn *gan-an/pùpọ̀* |
| Èso náà *sáré* hù | Èso náà *tètè* hù |

Ní àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, ó hàn gbangba pé àwọn ọ̀rọ̀ bíi *sáré, lọ, yára,* àti *tó* jẹ́ ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n, ìdí nìyí tí a fi lè fí ọ̀rọ̀- aṣẹ̀pọ́n mìíràn rọ́pò wọn láìsí ìyípadà nínú ìtumọ̀ ẹ̀hun tí wọ́n ti jẹ yọ. Elédè Yorùbá mọ̀ pé a kò lè fi ọ̀rọ̀- aṣẹ̀pọ́n rọ́pò ọ̀rọ̀-ìṣe nínú gbólóhùn bí a ṣe ṣe lókè yìí, ọ̀rọ̀- aṣẹ̀pọ́n nìkan ni a lè fi ọ̀rọ̀- aṣẹ̀pọ́n rọ́pò nínú gbólóhùn.

Bí a bá yọ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe tí àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún wọ̀nyí ń pọ́n kúrò nínú àwọn gbólóhùn tí wọ́n ti jẹ yọ, tí ó sì wá ku àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún nìkan, ìsọ àìṣeégbà ni gbólóhùn náà máa já sí tàbí kí ìtumọ̀ tí gbólóhùn fún wa yàtọ̀ sí ìtumọ̀ tí a ní lọ́kàn nígbà tí a lo àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí.

| | |
|---|---|
| Ọmọ náà *sáré* dàgbà | Ọmọ náà *sáré* |
| Adé sùn *lọ*. | Adé lọ. |
| Ó *yára* gun igi | *Ó *yára* igi |
| Oúnjẹ tí a rà lánàá ti *sáré* tán | *Oúnjẹ tí a rà lánàá ti *sáré* |
| Ọbẹ̀ náà *dùn* tó | Ọbẹ̀ náà *dùn* |
| Èso náà *sáré* hù. | *Èso náà *sáré*. |

Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún tí ó bá jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, àwọn tí ó bá jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe.

Àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n mìíràn tí a máa ń lò láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n àfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ẹ̀hun àpólà ìṣe ni a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ ní ìsàlẹ̀ yìí.

| | |
|---|---|
| Olú *bá ọmọ náà* ra aṣọ ní ọjà. | Ọpẹ́ *bá Òjó* se ọbẹ̀. |
| Ọkùnrin náà ti *ti oko* dé kí ìyàwó rẹ̀ tó bímọ. | Mo *ti Ìbàdàn* lọ sí Ìjàyè. |
| Ìyàwó ọkùnrin náà *fi èékán* dá àrà sí i lára. | Ó *fi ẹnu* wa ọkọ̀. |

Àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n ní àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí ni *bá ọmọ náà, bá Òjó, ti oko, ti Ìbàdàn, fi èékán* àti *fi ẹnu*. Àbùdá àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n ni pé wọ́n ní ọ̀rọ̀- aṣẹ̀pọ́n àti àbọ̀ tí wọ́n jìjọ jẹ̀ ẹ̀pọ́n

aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe. Àbùdá yìí ni wọ́n fi yàtọ̀ sí àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n tí wọ́n jẹ́ kìkì ọ̀rọ̀ aṣẹ̀pọ́n nìkan láìsí àbọ̀ tí ó tẹ̀lé wọn.

Àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) méjèèjì ni wọ́n lè jẹ yọ pọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe. Bí ìjẹyọpọ̀ báyìí bá wáyé, ó dàbí ẹni pé àpólà aṣẹ̀pọ́n tí kò ní àbọ̀ ni ó kọ́kọ́ máa jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe kí àpólà aṣẹ̀pọ́n tí ó ní àbọ̀ tó tẹ̀lé e. Àpẹẹrẹ ìjẹyọpọ̀ àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe méjèèjì nínú ìhun àpólà ìṣe ni mo fi hàn nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí. APEP ni àrokò fún àpólà aṣẹ̀pọ́n méjèèjì tí mo mẹ́nu bà. Ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni a sì fi sínú àkámọ́ [ ] bí wọ́n ṣe jẹ yọ nínú àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ.

Olú [APEP *kúkú lé]* *[*APEP *bá ọmọ náà]* ra aṣọ ní ọjà.
Ọpẹ́ *[*APEP *gbọ́dọ̀ tètè]* *[*APEP *bá Òjó]* se ọbẹ̀.
Ọkùnrin náà ti [APEP *tètè]* [APEP *ti oko]* dé kí ìyàwó rẹ̀ tó bímọ.
Ìyàwó ọkùnrin náà [APEP *ṣáà pàpà]* *[*APEP *fi èékán]* dá àrà sí i lára.
Ó [APEP *kàn dèdè]* *[*APEP *fi ẹnu]* wa ọkọ̀.

Bí àpólà aṣẹ̀pọ́n tí ó ní àbọ̀ nínú ìhun rẹ̀ bá jẹ yọ ṣáájú àpólà aṣẹ̀pọ́n tí kó ní àbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, ìsọ àìṣeégbà ni irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ máa jẹ́ gẹ́gẹ́ bí àwọn gbólóhùn márààrún ìsàlẹ̀ wọ̀nyí ṣe fi hàn.

*Olú *[*APEP *bá ọmọ náà]* [APEP *kúkú lé]* ra aṣọ ní ọjà.
*Ọpẹ́ *[*APEP *bá Òjó]* *[*APEP *gbọ́dọ̀ tètè]* se ọbẹ̀.
*Ọkùnrin náà ti [APEP *ti oko]* [APEP *tètè]* dé kí ìyàwó rẹ̀ tó bímọ.
*Ìyàwó ọkùnrin náà *[*APEP *fi èékán]* [APEP *ṣáà pàpà]* dá àrà sí i lára.
*Ó *[*APEP *fi ẹnu]* [APEP *kàn dèdè]* wa ọkọ̀.

Àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí jẹ́ àìṣeégbà nítorí pé ìpààrọ̀ ti dé bá áwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe méjèèjì.

## Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Atẹ̀lé Ọ̀rọ̀-Íṣe

Bí a ṣe rí àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún nínú ìhun àpólà ìṣe tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikúna aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí bẹ́ẹ̀ náà ni a rí àwọn tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú ẹ̀hun àpólà ìṣe.

Àpóla aṣẹ̀pọ́n náà ni a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe bí a ṣe máa ń ṣàmúlò wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí. Ní àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, a fi àwọn àpẹẹrẹ àpólà aṣẹ̀pọ́n tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí hàn, àwọn ni a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́. Àwọn ní *lọ, fọnfọn, kíákíá, tó, gan-an, púpọ̀, jáì,* àti *rí.*

| | |
|---|---|
| Adé sùn *lọ.* | Adé sùn *fọnfọn.* |
| Ó gun igi *kìàkìà* | Oúnjẹ tí a rà lánàá ti tán *kíákíá* |
| Ọbẹ̀ náà dùn *tó* | Ọbẹ̀ náà dùn *gan-an/pùpọ̀* |
| Ìṣẹ̀lẹ̀ náà burú *jáì* | Mi ò gbọ́ ọ̀rọ̀ burúkú yẹn *rí* |

Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí inú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí lè jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tààrà, gẹ́gẹ́ bí *lọ, fọnfọn, kíákíá* (tí ó tẹ̀lé *tán*), *tó, gan-an, púpọ̀* àti *burú* ṣe jẹ yọ. Ó sì ṣe é ṣe kí wọ́n (ìyẹn àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí) jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí àti àbọ̀ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí *kíákíá* (tí ó tẹ̀lé *gun igi),* àti *rí* (tí ó tẹ̀lé *gbọ́ ọ̀rọ̀ burúkú yẹn*) ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ṣe jẹ yọ. Gẹ́gẹ́ a ṣe ṣàlàyé ṣáájú, àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n wọ̀nyí jẹ́ kìkì ọ̀rọ̀ aṣẹ̀pọ́n nìkan láìsí ọ̀rọ̀ mìíràn nínú ìhun wọn.

Àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n mìíràn, tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, ni a fi hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

> Ọ̀gà wa ti lọ *sí ilé*[7].
> Ilé iṣe náà wà *ní Ìbàdàn.*
> Ọmọkùnrin náà ń rìn *bí ọba.*
> Kò sí ohun tí kìí tán *àfi ọlá Ọlọ́run.*
> Wọ́n kọrin *pẹ̀lú túlàsì.*
> Obìnrin náà ta aṣọ *fún mi.*

Ní àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n *sí ilé, ní Ìbàdàn, bí ọba, àfi ọla Ọlọ́run, pẹ̀lú túlàsì* àti *fún mi* ni wọ́n ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àwọn gbólóhùn tí wọ́n ti jẹ yọ. Àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n sí jẹ́ oníhùn-ún ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n àti àbọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ní wọ́n jẹ́ orí, àwọn náà ni *sí, ní, bí, àfi, pẹ̀lú* àti *fún.* Wọ́n sì gba *ilé, Ìbàdàn, ọba, Ọlọ́run, túlàsì* àti *mi* gẹ́gẹ́ bí àbọ̀.

Ní àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n alákànpọ̀[8] *lọ́hùn-ún, ṣáájú (síwájú), síbí,* àti *nínú* ni wọ́n jẹ́ orí.

> Ẹ̀gbọ́n yín wà *lọ́hùn-ún.*
> Àwọn ọmọdé náà tí lọ *ṣáájú (síwájú) yín.*
> Akẹ́kọ̀ọ́ náà wá *síbí.*
> A rí ọ̀gá wa *nínú ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́.*
> Mo rí i *nínú àwọn ilé ńlá ìsàlẹ̀ yìí.*
> Olú kó àwọn bàtà náà *sínú àpò ńlá méjì.*

Ó dàbí ẹni pé àpólà aṣẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí méjèèjì lè tẹ̀lé ara wọn nínú ìhun àpólà ìṣe. Ìyẹn àpólà aṣẹ̀pọ́n tí ó jẹ́ kìkìdá ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n àtí èyí tí ó jẹ́ ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n àti àbọ̀. Àmọ̀ kò dàbí ẹni pé ìjẹyọpọ̀ yìí wọ́pọ̀ rárá. Àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí ni ibi ti ìjẹyọpọ̀ àwọn méjèèjì ti wáyé.

> Adé sùn *lọ nínú ọkọ̀.*
> Adé sùn *fọnfọn sínú ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́*
> Oúnjẹ tí a rà lánàá ti tán *kíákíá ní àárọ̀ yìí*
> Ó gun igi *kìàkìà ṣáájú ìṣẹ̀lẹ̀ náà*

Àwọn ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí mìíràn ni a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí Ọ̀jọ̀gbọ́n-àgbà Awobuluyi ṣe fi yé wa.

> Ẹ ẹ́ lọ *ire (*lọọ*re)* (ọ̀rọ̀-orúkọ)
> Ṣe é *bí mo ti wí* (àpólà orúkọ)
> A ti jọ ń fa ọ̀rọ̀ yìí bọ̀ *(ó) ti pẹ́* (odidi gbólóhùn)
> Ohun tí a ti ń wí nìyí *ó ju ogún ọdún* (odidi gbólóhùn) (Awobuluyi, 2013, o.i. 166)

---

[7] Àpólà Atọ́kùn (APAT) ni a mọ àwọn ẹ̀hun bíi ***sí ilé, ní Ìbàdàn, pẹ̀lú túlàsì*** àti ***fún mi*** tẹ̀lẹ̀ ní ibi ti àwọn ọ̀rọ̀ bíi ***sí, ní, pẹ̀lú*** àti ***fún*** sì jẹ́ Ọ̀rọ̀ Atọ́kùn (AT). Wo Bamgoṣe (1972, 1990), Awobuluyi (1978, 1982, 2013), Yusuf (1995) àti Taiwo (2014). Ṣùgbọ́n Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) àti Ọ̀rọ̀ Aṣẹ̀pọ́n (EP) ni wọ́n jẹ́ nítorí pé iṣẹ́ ẹ̀pọ́n ni wọ́n ń ṣe fún ọ̀rọ̀-ìṣe (IṢ) aṣorí nínú Àpólà Ìṣe (APIṢ).

[8] Wo Táíwò (2011, o.i 115-200) lórí ọ̀rọ̀-alákànpọ̀ nínú èdè Yorùbá, pàápàá (o.i. 120-122) fún àlàyé lórí ọ̀rọ̀-atọ́kùn alákànpọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀-atọ́kùn (AT) wọ̀nyí ni a yà sọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n (EP) nínú bébà yìí.

**Ẹ̀pọ́n Aṣàmúpé nínú Ìhun Àpólà Ìṣe**

Nínú ìhun àpólà ìṣe, àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ kan wà tí wọ́n gbọ́dọ̀ jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí bẹ́ẹ̀ tó lè kún. Ìyẹn ni pé, ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nílò àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí à ń sọ yìí láti mú kí ìtumọ̀ rẹ̀ pé. Àwọn wúnrẹ̀n tí wọ́n máa ń mú ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé yìí ni a mọ̀ sí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé. Àpẹẹrẹ wọn ni a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí.

Olú san *owó ọkọ̀ náà*/Olú san *án*
Adé mọ *ilé náà*/Adé mọ̀ *ọ́n*
Ọmọ náà ta *gìtá*/Ọmọ náà ta *á*

Ọmọ náà pa *eku yẹn*/Ọmọ náà pa *á*
Adé mọ *ilé náà*/Adé mọ *ọ́n*
Ọmọ náà ta *gìtá*/Ọmọ náà tà *á*

Àwọn àpólà orúkọ tí a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé fún àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tí wọ́n jé yọ tẹ̀lé. Àwọn ni wọ́n mú ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí náà pé. Láìjẹ́ pé wọ́n jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, ìsọ àìṣeégbà ní gbólóhùn náà yóò fún wa gẹ́gẹ́ bí àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí ṣe fi hàn.

*Olú san    *Ọmọ náà pa    *Adé mọ    *Ọmọ náà ta

Àbùdá àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe bíi *san, pa, mọ* àti *ta* tí wọ́n jẹ yọ nínú àwọn ìsọ/gbólóhùn àìṣeégbà òkè yìí ni pé wọ́n gbọ́dọ̀ yan àpólà orúkọ àbọ̀ tí ó gbọ́dọ̀ jẹ yọ tẹ̀lé wọn, láìjẹ́ bẹ́ẹ̀, ìsọ tàbí gbólóhùn tí wọ́n bá ti jẹ yọ kò ní ṣe é gbà. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú àwọn gbólóhùn aṣeégbà òkè wọ̀nyí ni *owó ọkọ̀ náà*/*án*, *eku yẹn*/*wọ́n*, *ilé náà*/*ọ́n* àti *gìtá*/*á*. Àìjẹyọ wọn tẹ̀lé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni ó fà á tí ìsọ fi jẹ́ àìṣeégbà.

Yàtọ̀ sí àwọn àpólà orúkọ àbọ̀ tí wọ́n jẹ́ àmúpé fún ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú ìhun àpólà ìṣe tí a ṣàlàyé lókè yìí, àpapọ̀ àpólà orúkọ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n máa ń jẹ yọ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé fún ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe. Àpẹẹrẹ wọn ni a fi hàn nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

Obìnrin náà fi *owó sí àpò*
Ọmọ máà yọ *ìyá rẹ̀ ní ẹnu*
Wọ́n ka *ọ̀gá wọn sí pàtàkì*
Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà dẹ *eti sí ilẹ.*

Ẹṣin náà ta *olówó rẹ̀ ní ìpá*
Ìyàwó náà kọ *ojú sí ibòmíràn*
Ọmọbìnrin náà fọ̀ *Olú ní etí*

Àpólà orúkọ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n tí wọ́n jẹ yọ papọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí ni [APOR *owó]*[APEP *sí àpò*], [APOR *olówó rẹ̀*] [APEP *ní ìpá]*, [APOR *ìyá rẹ̀* [APEP *ní ẹnu]*, [APOR *ojú* [APEP *sí ibòmíràn]*, [APOR *ọ̀gá wọn*[APEP *sí pàtàkì]*, [APOR *Olú* [APEP *ní etí]*, àti [APOR *eti* [APEP *sí ilẹ*]

*Obìnrin náà fi
*Ọmọ máà yọ
*Wọ́n ka
*Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà dẹ

*Ẹṣin náà ta
*Ìyàwó náà kọ
*Ọmọbìnrin náà fọ̀

Àwọn ìsọ/gbólóhùn òkè wọ̀nyí jẹ́ àìṣeégbà nítorí pé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe inú wọn kò ní ẹ̀pọ́n aṣàmúpé tí ó jẹ yọ tẹ̀lé wọn, bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n gbọ́dọ̀ ní àmúpé bẹ́ẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe yìí kan náà gba ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, wọ́n tún jẹ́ àìṣeégbà nítorí pé àpòlà orúkọ nìkan ni ẹ̀pọ́n aṣàmúpé tí ó jẹ yọ tẹ̀lé wọn.

*Obìnrin náà fi *owó*
*Ọmọ máà yọ *ìyá rẹ̀*

*Ẹṣin náà ta *olówó rẹ̀*
*Ìyàwó náà kọ *ojú*

| | |
|---|---|
| Wọ́n ka *ọ̀gá wọn* | *Ọmọbìnrin náà fọ́ *Olú* |
| *Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà dẹ *eti* | |

Ọ̀kan nínú gbólóhùn òkè yìí jẹ́ aṣeégbà, ìyẹn *Wọ́n ka ọ̀gá wọn,* ṣùgbọ́n ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ sí *Wọ́n ka ọ̀gá wọn sí pàtàkì* tí ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ wa.

Yàtọ̀ sí àkíyèsí tí a tún ṣe lókèè yìí, pé yíyọ tí a yọ àpólà aṣẹ̀pọ́n kúrò nínú ìhun àpólà ìṣe ni ó fa àìṣeégbà àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí, a tún ṣàkíyèsí pé bí a bá yọ àpólà orúkọ kúrò nínú ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe tí ó wá ku àpólà aṣẹ̀pọ́n níkan, gbólóhùn náà kò ní ṣe ẹ gbà bákan náà. Ìdí abájọ nìyí tí àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí fi jẹ́ àìṣeégbà. Ibi tí ó yẹ kí àpólà orúkọ ti jẹ yọ, ṣùgbón tí a ti yọ kúrò ni àmì ìṣófo – wà nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | |
|---|---|
| *Obìnrin náà fi - *sí àpò* | *Ẹṣin náà ta -- *ní ìpá* |
| *Ọmọ máà yọ -- *ní ẹnu* | *Ìyàwó náà kọ -- *sí ibòmíràn* |
| *Wọ́n ka -- *sí pàtàkì* | *Ọmọbìnrin náà fọ́ -- *ní etí* |
| *Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà dẹ -- *sí ilẹ.* | |

Àmọ̀ ṣáá, ó ṣe é ṣe kí àpólà aṣẹ̀pọ́n nìkan tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe. Àpẹẹrẹ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé bẹ́ẹ̀ ní a kọ ní àkọhàn dẹ́gbẹ̀ nínú àwọn gbólohùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | |
|---|---|
| Àpapọ̀ owó náà kú *sí múrí mẹ́wàá.* | Wàhálà rẹ̀ já *sí asán* |
| Ọdẹ náà ti já *sí ojú ọ̀nà.* | Ìyá àgbà n gbé *ní Mọ́níyà.* |
| Wàhálà rẹ́ kò mọ *ní kékeré.* | Ọ̀gá wọn yọ *sí wọn lójìjìì.* |
| Wọ́n fi *sí alẹ́ ọ̀la.* | Ọnà náà pín *sí márùn-ún* |

Àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí ni ìwọ̀nyí: *sí múrí mẹ́wàá, sí asán, sí ojú ọ̀nà, ní Mọ́níyà, ní kékeré, sí wọn lójìjìì, sí alẹ́ ọ̀la* àti *sí márùn-ún.* Ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni wọ́ ní ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n àti àbọ̀. Bí a bá yọ àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n wọ̀nyí kúrò, ìsọ àìṣeégbà ni àwọn tó kù máa jẹ́ gẹ́gẹ́ bí à ṣe rí i nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | |
|---|---|
| *Àpapọ̀ owó náà kú | *Wàhálà rẹ̀ já |
| *Ọdẹ náà ti já | *Ìyá àgbà n gbé |
| *Wàhálà rẹ́ kò mọ | *Ọ̀gá wọn yọ |
| *Wọ́n fi | *Ọnà náà pín |

Àpólà aṣẹ̀pọ́n mìíràn tí a tún máa ń lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé fún ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni ó jẹ́ kìkì ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n nìkan. Àwọn náà ni *sánsán, yòò* àti *fáfá* ni a kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | | |
|---|---|---|
| Ọbẹ̀ náà ta *sansan.* | Aṣọ náà bẹ́ *yòò.* | Ọmọ náà já *fáfá.* |

Bí a bá yọ àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n aṣàmúpé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí wọ̀nyí kúrò nínú ẹ̀hun tí wọ́n ti jẹ yọ, ìtumọ̀ èyí tí ó kù yóò yàtọ̀ sí ìtumọ̀ tí a ní lọ́kàn tàbí kí ó jẹ́ ìsọ àìṣeégbà ni ó máa kù.

| | | |
|---|---|---|
| Ọbẹ̀ náà ta. | Aṣọ náà bẹ́. | *Ọmọ náà já. |

Àwọn àpẹẹrẹ méjì àkọ́kọ́ jẹ́ ìsọ aṣeégbà ṣùgbọ́n ìtumọ̀ wọn yàtọ̀ sí ti gbólóhùn àpẹẹrẹ wa, àpẹẹrẹ kẹta kò ṣe é gbà rárá. Ohun tí ó fa èyí ni bí a ṣe yọ àwọn ẹ̀pọ́n aṣàmúpé kúrò nínú ìhun àpólà ìṣe.

**Tẹ̀léǹtẹ̀lé Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe**

Oríṣi ẹ̀pọ́n méjì ni a yà sọ́tọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ìjíròrò àti àwọn àlàyé wa ṣe fi yé wa. Àwọn ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún àti ẹ̀pọ́n aṣàmúpé.

Ẹ̀pọ́n aṣàfikún lè jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí kí ó jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe, ṣùgbọ́n ẹ̀pọ́n aṣàmúpé ní tirẹ̀ máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, kìí jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí rárá. Ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ àpólà aṣẹ̀pọ́n ni a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún, a sì máa ń lo ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ àpólà orúkọ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé. Bí àwọn ẹ̀pọ́n wọ̀nyí ṣe máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn nínú ìhun àpólà ìṣe nìyí.

Ní àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí, ìyẹn (a-ẹ), ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí *mọ, san, pa* àti *ta* gbọ́dọ̀ gba àpólà orúkọ àbọ̀ aṣàmúpé gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n nínú àpólà ìṣe, àpólà orúkọ àbọ̀ yìí jẹ́ kànńpá. Àmọ́ ṣáá, àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún lè jẹ yọ tàbí kí wọ́n máà jẹ yọ. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, ìyẹn àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) mẹ́ta ní wọ́n jẹ yọ, àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí méjì ní (a àti b), ìyẹn APEP níkan ní (d àti e) sì jẹ yọ tẹ̀lé ẹ̀pọ́n aṣàmúpé. Ní àpẹẹrẹ (ẹ), kò sí ẹ̀pọ́n aṣàfikún kankan, ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nìkan ni ó wà nínú àpólá ìṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí.

a. Adé [APIṢ kàn dédé bá Òjó mọ ilé náà tán ṣáájù ìṣẹ̀lẹ̀ náà APIṢ]
APEP APEP APEP IṢ APOR APEP APEP
aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

b. Olú [APIṢ kúkú lé bá ọmọ náà san owó ilé-ìwé rẹ̀ pátá ní ọla APIṢ].
APEP APEP APEP IṢ APOR APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

d. Ọpẹ́ [APIṢ gbọ́dọ̀ tètè bá Òjó pa eku yẹn ní àárọ̀ yìí APIṢ]
APEP APEP APEP IṢ APOR APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

e. Ìyàwó ọkùnrin náà [APIṢ ṣáà pàpà fi èékán ta gìtá ní àkókò àjọ̀dún náà APIṢ]
APEP APEP APEP IṢ APOR APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

ẹ. Ìyàwó ọkùnrin náà [APIṢ ta gìtá APIṢ]
IṢ APOR
aṣàmúpé

Nínú àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, APIṢ, ìyẹn àpólà ìṣe, ni a fi sí inú àkámọ́ onígun [ ], àwọn àpólà orúkọ tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàárà, ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí sí tẹ̀lé ẹ̀pọ́n aṣàmúpé. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe (ìyẹn àpólà aṣẹ̀pọ́n) ni wọ́n sì jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàárá. Àlàyé yìí ní mo fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

[APIṢ (APEP) (APEP) (APEP) IṢ APOR (APEP) (APEP)APIṢ]

Àwọn àrokò tí a fi sínú àkámọ́ afìwọ̀fún-hàn, ìyẹn ( ), fi hàn pé ìwọ̀fún ni wọ́n jẹ́, wọn kìí ṣe kàńpá rárá. Èyí já sí pé IṢ, ìyẹn ọ̀rọ̀-ìṣe, tí ó jẹ́ orí, àti APOR nì kan ni kàńpá nínú àpólà ìṣe (APIṢ) àwọn yòókù jẹ́ ìwọ̀fún.

Ní àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ méjì ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, àpapọ̀ àpólà orúkọ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n ni wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé, tí wọ́n sì jẹ́ kàńpá nínú ìhun àpólà ìṣe. Àmọ́ ṣáá, a tún rí àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún

atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe méjì méjì, APEP àti APEP, tí wọ́n jẹ yọ tẹ̀lé àwọn ẹ̀pọ́n aṣàmúpé tààrà. Bákan náà, àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájù ọ̀rọ̀-ìṣe mẹ́ta mẹ́ta jẹ́ yọ pẹ̀lú.

Ọmọ náà [APIṢ tiẹ̀ kúkú bá Òjó yọ ìyá rẹ̀ ní ẹnu púpọ̀ lẹ́ẹ̀kan (ní ẹ̀ẹ̀kan) APIṢ]
APEP APEP APEP IṢ APOR APEP APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

Àwọn òṣìṣẹ́ náà [APIṢ ṣáà pàpà bá wọn dẹ eti sí ilẹ gan-an nínú ìpàdé náà APIṢ].
APEP APEP APEP IṢ APOR APEP APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

Àwọn òṣìṣẹ́ náà [APIṢ dẹ eti sí ilẹ APIṢ].
IṢ APOR APEP
aṣàmúpé

Bí àwọn ẹ̀pọ́n ṣe máa ń jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe tí wọ́n ni ọ̀rọ̀-ìṣe agbamúpé alápóláà orúkọ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n ni a fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

[APIṢ (APEP) (APEP) (APEP) IṢ APOR APEP (APEP) (APEP)APIṢ]

APOR (àpólà orúkọ) àti APEP (àpólà aṣẹ̀pọ́n) aṣàmúpé nìkan ni kàn̄pá nínú ìhun APIṢ, gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn lókè, APOR jẹ yọ tẹ̀lé IṢ tààrà, nígbà tí APEP jẹ yọ tẹ̀lé APOR. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú àti atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe asorí jẹ́ ìwọ̀fún.

Bí ó bá jẹ́ àpólà aṣẹ̀pọ́n nìkan ni ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe, òun náà nìkan ní kàn̄pá lára àwọn ẹ̀pọ́n tí ó bá wà nínú àpólà ìṣe. Àwọn àpẹẹrẹ ni a kọ sí ìsàlẹ̀ yìí.

Ọdẹ náà ti [APIṢ kúkú pẹ̀lú wọn já sí ojú ọ̀nà gan-an ní àárọ̀ yìí APIṢ].
APEP APEP IṢ APEP APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

Ìyá àgbà [APIṢ bá wọn gbé ní Mọ́níyà láti ọdún tí ó kọjá APIṢ].
APEP IṢ APEP APEP
Aṣàfikún àṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

Ìyá àgbà [APIṢ gbé ní Mọ́níyà APIṢ].
IṢ APEP
aṣàmúpé

Bí àwọn ẹ̀pọ́n ṣe máa ń jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe tí wọ́n ni ọ̀rọ̀-ìṣe agbamúpé alápóláà aṣẹ̀pọ́n a fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

[APIṢ (APEP) IṢ APEP (APEP) (APEP)APIṢ]

APEP, àpólà aṣẹ̀pọ́n aṣàmúpé jẹ yọ tẹ̀lé IṢ, ìyẹn ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, tààrà nínú àpólà ìṣe, gẹ́gẹ́ bí a ṣe fi hàn lókèè. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáaju àti atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí lè jẹ yọ tàbí kí wọ́n máà jẹ yọ.

Bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé bá jẹ́ ọ̀rọ̀ aṣẹ̀pọ́n nìkan nínú ìhun àpólà ìṣe, òun náà ni kàn̄pà. Àmọ́ sáá, àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú àti atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí lè jẹ yọ tàbí kí wọ́n máà jẹ yọ.

Obìnrin náà [APIṢ kúkú ṣì já fáfá gan-an ní ojú tiwa APIṢ]

APEP APEP IṢ APEP APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

Obìnrin náà [APIṢ kúkú ṣì já fáfá APIṢ]
APEP APEP IṢ APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé

Aṣọ náà [APIṢ ṣì pàpà bẹ́ yòò nínú omi dúdú síbẹ̀síbẹ̀ APIṢ]
APEP APEP IṢ APEP APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàmúpé [aṣàfikún atẹ̀lé]

Aṣọ náà [APIṢ bẹ́ yòò APIṢ]
IṢ APEP
aṣàmúpé

Bí àwọn ẹ̀pọ́n ṣe jé yọ nínú ìhun àwọn àpólà ìṣe tí wọ́n wà lókèè nìyí.

[APIṢ (APEP) (APEP) IṢ APEP (APEP) (APEP) APIṢ]

APEP aṣàmúpé jẹ yọ tẹ̀lé IṢ, ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tààrà nínú ìhun àpólá ìṣe, àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú àti atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí lè jẹ yọ tàbí kí wọ́n máà jẹ yọ.

Bí ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí bá jẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe aláìgbàmúpé, irú ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀ níkan ni ó pọn dandan fún láti wà nínú ìhun àpólá ìṣe. Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú àti atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí lè jẹ yọ tàbí kí wọ́n máà jẹ yọ.

Olú [APIṢ tiẹ̀ kúkú sùn fọnfọn sórí àga APIṢ]
APEP APEP IṢ APEP APEP
Aṣàfikún aṣáájú aṣàfikún atẹ̀lé

Ọ̀rọ̀ náà [APIṢ sáà tóbi jù ní ẹnu wa APIṢ]
APEP IṢ APEP APEP
Aṣàfikún aṣáaju aṣàfikún atẹ̀lé

Ọbẹ̀ náà [APIṢ sáà kúkú dùn púpọ̀ APIṢ]
APEP APEP IṢ APEP
Aṣàfikún aṣáaju aṣàfikún atẹ̀lé

Ọbẹ̀ náà [APIṢ dùn APIṢ]
IṢ

[APIṢ (APEP) (APEP) IṢ (APEP) APIṢ]

Nínú ìhun àpólà ìṣe, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe fojú hàn lókèè yìí, IṢ, ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nìkan ni ó jẹ kàǹpá, ìwọ̀fún ni àwọn ẹ̀pọ́n tí wọ́n bá jẹ yọ nínú rẹ̀ jẹ́.

Àwọn àlàyé àti ìjírórò tí a ṣe wọ̀nyí fi àwọn àkíyèsí wọ̀nyí hàn nípa bí àwọn ẹ̀pọ́n ṣe máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ara nínú ìhun àpólà ìṣe:

- Àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìgbàbọ̀ ni ó máa ń kọ́kọ́ jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, lẹ́yìn náà ni àpólà aṣẹ̀pọ́n agbàbọ̀ aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe máa jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí táárá.
- Ẹ̀pọ́n aṣàmúpé máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí agbàmúpé tààrà nínú ìhun àpólà ìṣe.

- Bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé bá jẹ́ APOR àti APEP, APOR ni ó máa kọ́kọ́ jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí agbàmúpé tààrà, lẹ́yìn náà ni APEP yóò jẹ yọ tẹ̀lé APOR.
- Àpólà aṣẹ̀pọ́n, APEP, aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe lè jẹ́ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú ìhun àpólà ìṣe.
- Ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí aláìgbàmúpé kìí gba ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe.

## Ìsọníṣókí

A ki àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí *ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àsópọ̀ ọ̀rọ̀ tí ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ orí rẹ̀ tí a sì a lè lò gẹ́gẹ́ bí kókó gbólóhùn nínú gbólóhùn aṣeégbà*. Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a pín ìhun àpólà ìṣe sí. Àwọn ni orí àti ẹ̀pọ́n. Ọ̀rọ̀-ìṣe ni orí nínú ìhun àpólà ìṣe. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti mọ̀, orí nìkan ni kànńpá nínú ìhun àpólà ìṣe, ìwọ̀fún ni ẹ̀pọ́n jẹ́. A ki ẹ̀pọ́n gẹ́gẹ́ *bí ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí a lò nínú ìhun àpólà ìṣe láti fi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé*. Oríṣi ẹ̀pọ́n méjì ni a yà sọ́tọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe, àwọn ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún àti ẹ̀pọ́n aṣàmúpé. Àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe ni àpólà orúkọ àbọ̀ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n. Àpólà aṣẹ̀pọ́n náà ni a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí aṣàfikún nínú ìhun àpólà ìṣe. Oríṣi ẹ̀pọ́n aṣàfikún méjì tí a yà sọ́tọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe. Àwọn ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe àti ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe. Ẹ̀pọ́n aṣàfikún lè jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí kí ó jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe, ṣùgbọ́n ẹ̀pọ́n aṣàmúpé ní tirẹ̀ máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, kìí jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí rárá.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Awóbùlúyì, O. 1972. “On the Classification of Yorùbá Verb”, nínú Bámgbóṣé (olótùú) o.i. 119-134.

Awóbùlúyì, Ọ. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.

Awóbùlúyì, O. 1982. “The Yorùbá Verb Phrase”, nínú Afọlayan, A. (olótùú) *Yorùbá Language and Literature,* Ìbàdàn: UPL and Unife Press. pp. 225-246.

Awobuluyi, Ọ. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*. Oṣogbo: ATAM Limited

Bámgbóṣé, A. 1966. *A Grammar of Yorùbá,* Cambridge:CUP

Bámgbóṣé, A. 1967. *A Short Yorùbá Grammar.*Ibadan: HEB (Nigeria) Ltd

Bámgbóṣé, A. 1972a. “Introduction”, nínú Bámgbóṣé (olótùú) o.i. 1 - 17

Bámgbóṣé, A. 1972b. (olótùú) *The Yorùbá Verb Phrase,* Ìbàdàn: UPL.

Bámgbóṣé, A. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: UPL.

Taiwo, O. 2011. *Mofọ́lọ́jì: Àtúnṣe kejì*: Ibadan, Akada Universal Books

Taiwo, O 2014. *Ìsọ̀rí Ọ̀rọ̀ Èdè Yorùbá I*: Ibadan, DLC, UI

Táíwò, O. 2018a. Òṣuwọ̀n fún dídá Ọ̀rọ̀-Ìṣe mọ̀ ní Èdè Yorùbá. Bébà tí a kà ní IBALSG Colloquim, Yunifásítì Ìbàdàn. January 2018 tí a sì gbé jáde nínú *JOLAN (Journal of the Linguistic Association of Nigeria)* Volume 21 No 1 (2018) o.i. 76 - 96

Táíwò, O. 2018b. Àgbéyẹ̀wò Oríkì Ọ̀rọ̀-Ìṣe Èdè Yorùbá. Bébà tí a kà ní IBALSG Colloquim, Yunifásítì Ìbàdàn. July 2018

Yusuff, Ọ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun: Ní Ìlànà Ìṣípayà Onídàrọ,* Ijebu-ode: Ṣebiotimọ Publications.